Nọmba OMB 0607-1006: Ìfọwọ́si Nparí ní 11/30/2021

# Ìtọ́sọ́nà rẹ sí Ìkànìyàn 2020

## Bí o ṣe lè Fèsì sí Ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò orí Ìwé ti Ìkànìyàn 2020



United States® Census 2020

# Káàbọ̀ sí Ìkànìyàn 2020



## Gbogbo ènìyàn ló ṣe pàtàkì.

Èròngbà ìkànìyàn yìí ni láti ka gbogbo ènìyàn tó wà láàyè ní ìlẹ̀ U.S. lẹ́ẹ̀kan, ẹ̀ẹ̀kan ṣoṣo, àti ní ibi tí ó yẹ. A nílò ìrànwọ́ rẹ láti rí dájú pé gbogbo ènìyàn tí ń gbé ní agbègbè rẹ ni a kà.



## Détà ìkànìyàn ṣe pàtàkì.

Ìwé òfin Ilẹ̀ Amẹ́ríkà fi àyè gba ṣíse ìkànìyàn ní ọdún mẹ́wàá mẹ́wàá. Àwọn èsì náà ni a ń lò láti pinnu iye ìjókòó tí ìpínlẹ̀ kọ̀ọ̀kan ní nínú ilé ìgbìmọ̀ aṣòfin láti fa ààlà fún àwọn agbègbè ìdìbò, àti láti pinnu bí a ó ti lo ìnáwó ìjọba àpapọ̀ tó ju $675 billion lọ ní àwọn agbègbè tí àwọn ènìyàn ńgbé ní ọdún kọ̀ọ̀kan.



## Kíkópa jẹ́ ojúṣe rẹ gẹ́gẹ́ bíi ọmọ ìlú.

Píparí ìlànà ìkànìyàn yii ṣe pàtàkì; ó jẹ́ ọ̀nà láti kópa nínú ìjọba tiwantiwa, kí o sì wípé "Mo ṣe pàtàkí!"



## Àwọn èsì rẹ jẹ́ ohun àṣírí.

Òfin ìjọba àpapọ̀ ń dá ààbò bo àwọn ìdáhùn rẹ. A lè lo àwọn ìdáhùn rẹ láti pèsè ìtúpalẹ̀ détà, kò sì sí ilé-iṣẹ́ ìjọba tàbí ilé-ẹjọ́ kankan tó lè lòó lòdì sí ọ.



## Lo ìtọ́sọ́nà yìí láti parí dídáhùn àwọn ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò orí ìwé ti Ìkànìyàn 2020.

Àwọn Ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò orí ìwé ti Ìkànìyàn 2020 yóò dé sínú àwọn àpótí lẹ́tà àti ní ẹnu ọ̀nà kọ̀ọ̀kan káàkiri orílẹ̀-èdè.

# Kí O tó Bẹ̀rẹ̀

1. Wá ìwé ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò rẹ, kí o sì ṣíi sí ojú-ìwé àkọ́kọ́.

2. Lo àlàyé tó wà nínú ìtọ́sọ́nà ní èdè Yorùbá yìí láti sààmì sí àwọn ìdáhùn rẹ lórí ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò orí ìwé náà tí a kọ ní èdè Gẹ̀ẹ́sì. **MÁṢE KỌ ÀWỌN ÌDÁHÙN RẸ SÓRÍ ÌTỌ́SỌ́NÀ YÌÍ.**

3. Kí o tó dáhùn ìbéèrè àkọ́kọ́, ka àwọn ènìyàn tí ń gbé inú ilé yìí, nínú ibùgbé olókè ẹlẹ́yọkọ̀ọ̀kan yìí, tàbí nínú ilé aláàgbéká yìí nípa lílo àwọn ìtọ́ni tó wà nísàlẹ̀ yìí.

# Tani a ní láti Kà

**Ka àwọn ènìyàn tí ń gbé inú ilé yìí, nínú ibùgbé olókè ẹlẹ́yọkọ̀ọ̀kan yìí, tàbí nínú ilé aláàgbéká yìí:**

- Ka gbogbo àwọn ènìyàn, pẹ̀lú ọmọ-ọwọ́, tí ń gbé tó sì ń sùn níbí ní ọ̀pọ̀ ìgbà.

- Tí kò bá sí ẹni tí ń gbé tàbí sùn ní àdírẹ́ẹ̀sì yìí ní ọ̀pọ̀ ìgbà, dáhùn lórí ayélujára.

**Ìkànìyàn náà gbọ́dọ̀ ṣe ètò láti ka àwọn ènìyàn tí kò ní ibùgbé láti gbé pé títí:**

- Tí ẹnìkan tí kò ní ibùgbé láti gbé pé títí bá wà níbí ní Ọjọ́ kìíní, Oṣù kẹrin, ọdún 2020, ka ẹni náà.

**Ilé-iṣẹ́ Ìkànìyàn tún ń ṣe ètò láti ka àwọn tó wà ní ilé-ìwé gíga àti àwọn ibi míràn:**

- Máṣe ka ẹnikẹ́ni tó wà ní ibùgbé ìtọ́jú aláàárẹ̀, ẹ̀wọ̀n, ilé túbú, ibi ìtìmọ́lé àwọn ọ̀daràn, abbl., ní Ọjọ́ kìíní, Oṣù kẹrin, ọdún 2020.

- Máṣe kọ àwọn ènìyàn wọ̀nyí sínú ìwé ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò rẹ, kódà tí wọ́n bá máa padà láti gbé ibí lẹ́yìn tí wọ́n bá fi kọ́lẹ́ẹ̀jì, ibùgbé ìtọ́jú aláàárẹ̀, iṣẹ́ ológun, ẹ̀wọ̀n, abbl. Bí bẹ́ẹ̀kọ́, a le kà wọ́n lẹ́ẹ̀mejì.

Ka àwọn ìbéèrè àti ìtọ́ni lójú ìwé tí ó kàn. →
***Máṣe kọ àwọn ìdáhùn rẹ sórí ìtọ́sọ́nà yìí.***

# Pari àwọn ìbéèrè tí ó wà lójú-ìwé àkọ́kọ́

*MÁṢE KỌ ÀWỌN ÌDÁHÙN RẸ SÓRÍ ÌTỌ́SỌ́NÀ YÌÍ*

**1.** **How many people were living or staying in this house, apartment, or mobile home on April 1, 2020?**

***Number of people =*** ☐☐

Iye Àwọn Ènìyàn

**Ènìyàn mélòó ní ń gbé tàbí wà nínú ilé yii, nínú ibùgbé olókè ẹlẹ́yọkọ̀ọ̀kan yìí, tàbí nínú ilé aláàgbéká yìí ní Ọjọ́ kìíní, Oṣù kẹrin, ọdún 2020?**

**2.** **Were there any <u>additional</u> people staying here on April 1, 2020 that you <u>did not include</u> in Question 1?**

*Mark* ☒ *all that apply.*

- ☐ Children, related or unrelated, such as newborn babies, grandchildren, or foster children
- ☐ Relatives, such as adult children, cousins, or in-laws
- ☐ Nonrelatives, such as roommates or live-in babysitters
- ☐ People staying here temporarily
- ☐ No additional people

**Ǹjẹ́ ènìyàn <u>mìíràn</u> kankan yòówù ǹ gbé ibi ní Ọjọ́ kìíní, Oṣù kẹrin, ọdún 2020, ẹnití ìwọ <u>kò mẹ́nubà</u> nínú Ìbéèrè 1 bí?**

Sààmì ☒ sí gbogbo èyí tó kàn.

- Àwọn ọmọdé, tí ó tan mọ́ ọ tàbí tí kò tan mọ́ ọ, bíi ọmọ-ọwọ́ titun, ọmọ-ọmọ, tàbí àwọn ọmọ tí a gbà tọ́ (foster children)
- Àwọn ìbátan, bíi àgbàlagbà ọmọ, ọmọ ẹ̀gbọ́n tàbí àbúrò ìyá tàbí bàbá ẹni, tàbí àwọn àna
- Àwọn ẹlòmíràn tí kìí ṣe ìbátan, bíi àwọn alájọgbénúyàrá tabí àwọn olùbánitọ́jú-ọmọ tí ń bánigbé
- Àwọn ènìyàn tó ńgbé ibí yìí fún ìgbà díẹ̀
- Kò sí àfikún ènìyàn míràn mọ

**3.** **Is this house, apartment, or mobile home** — *Mark* ☒ *ONE box.*

- ☐ Owned by you or someone in this household with a mortgage or loan? *Include home equity loans.*
- ☐ Owned by you or someone in this household free and clear (without a mortgage or loan)?
- ☐ Rented?
- ☐ Occupied without payment of rent?

**Ǹjẹ́ ilé ni èyí, ibùgbé olókè ẹlẹ́yọkọ̀ọ̀kan, tàbí ilé aláàgbéká —**

Sààmì sí ☒ àpótí KANṢOṢO.

- Ìwọ tàbí ẹlòmíràn nínú ìdílé yìí ló ni pẹlú ètò yíyáwókọ́lé tàbí ètò ẹ̀yáwó? Fi ètò fífi ilé dúró fún ètò ẹ̀yáwó kún un.
- Ìwọ tàbí ẹlòmíràn nínú ìdílé yìí ló ni pẹ̀lú òmìnira (láìsí ètò yíyáwókọ́lé tàbí ètò ẹ̀yáwó kankan)?
- Àyágbé?
- Tó ńgbélé láì sanwó ilé?

**4.** **What is your telephone number?**

*We will only contact you if needed for official Census Bureau business.*

Telephone Number

☐☐☐ – ☐☐☐ – ☐☐☐☐

Nọmbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀

**Kíni nọmbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ rẹ?**

A ó kàn sí ọ tí a bá nílò rẹ fún isẹ Ilé-iṣẹ́ Ìkànìyàn nìkan.

# Parí àwọn ìbèèrè ni apá òsì ojú ìwé kejì

## *MÁṢE KỌ ÀWỌN ÌDÁHÙN RẸ SÓRÍ ÌTỌ́SỌ́NÀ YÌÍ*


**5.** Please provide information for each person living here. If there is someone living here who pays the rent or owns this residence, start by listing him or her as Person 1. If the owner or the person who pays the rent does not live here, start by listing any adult living here as Person 1.

**What is Person 1's name?** *Print name below.*

First Name MI

Last Name(s)



Jọ̀wọ́ pèsè àlàyé fún ẹnìkọ̀ọ̀kan tó ń gbé ibí yìí. Ti ẹnikẹ́ni bá ńgbé ibí yìí tó nsanwó ilé àyágbé náà tàbí tó ni ilé tí ènìyàn ńgbé yìí, bẹ̀rẹ̀ nípa kíkọ orúkọ ẹni náà gẹ́gẹ́ bíi Ẹni Kìíní. Ti onílé tàbí ẹni tí ń sanwó ilé kò bá ń gbé ibí yìí, bẹ̀rẹ̀ nípa kíkọ orúkọ àgbàlagbà kankan yòówù tó ngbé ibí yìí gẹ́gẹ́ bíi Ẹni Kìíní.

**Kíni orúkọ Ẹni Kìíní?**


**6.** **What is Person 1's sex?** *Mark* ☒ *ONE box.*

☐ Male ☐ Female

**Ǹjẹ́ Ẹni Kìíní jẹ́ ọkùnrin tàbí obìnrin bí?** Sààmì sí ☒ àpótí KANṢOṢO.

- Ọkùnrin
- Obìnrin


**7.** **What is Person 1's age and what is Person 1's date of birth?** *For babies less than 1 year old, do not write the age in months. Write 0 as the age.*

*Print numbers in boxes.*

Age on April 1, 2020 ___ years Month Day Year of birth



**Kíni ọjọ́-orí Ẹni Kìíní ati kíni ọjọ́ tí a bí Ẹni Kìíní?**

Fún àwọn ọmọ-ọwọ́ tí ọjọ́-orí wọn kò tíì tó ọdún kan, máṣe kọ ọjọ́-orí ni oṣù. Kọ òdo gẹ́gẹ́ bí ọjọ́-orí.


**8.** **Is Person 1 of Hispanic, Latino, or Spanish origin?**

☐ **No**, not of Hispanic, Latino, or Spanish origin
☐ Yes, Mexican, Mexican Am., Chicano
☐ Yes, Puerto Rican
☐ Yes, Cuban
☐ Yes, another Hispanic, Latino, or Spanish origin – *Print, for example, Salvadoran, Dominican, Colombian, Guatemalan, Spaniard, Ecuadorian, etc.*

**Ǹjẹ́ Ẹni Kìíní jẹ́ Abínibí Hispanic, Latino tàbí Spain?**

- **Rárá**, kì í ṣe Abínibí Hispanic, Latino tàbí Spain
- Bẹ́ẹ̀ni, Ará Mexico, Ará Mexico pẹ̀lú Amẹ́ríkà, Abínibí Chicano
- Bẹ́ẹ̀ni, Ará Puerto Rico
- Béèni, Ará Kúbà
- Bẹ́ẹ̀ni, Abínibí Hispanic, Latino tàbí Spain mìíràn — Kọ àwọn lẹ́tà náà lọ́kọ̀ọ̀kan lái so wọ́n pọ̀, fún àpẹẹrẹ, Ará El Salvador, Ará Dòmíníkà, Ará Kọ̀lọ́mbíà, Ará Gọ̀tẹ́màlà, Ará Spain, Ará Èkúadò, abbl.

# Parí ìbèèrè ni apá ọ̀tún ojú ìwé keji

## *MÁṢE KỌ ÀWỌN ÌDÁHÙN RẸ SÓRÍ ÌTỌ́SỌ́NÀ YÌÍ*


**9. What is Person 1's race?**
*Mark* ☒ *one or more boxes* ***AND*** *print origins.*

☐ White – *Print, for example, German, Irish, English, Italian, Lebanese, Egyptian, etc.*

☐ Black or African Am. – *Print, for example, African American, Jamaican, Haitian, Nigerian, Ethiopian, Somali, etc.*

☐ American Indian or Alaska Native – *Print name of enrolled or principal tribe(s), for example, Navajo Nation, Blackfeet Tribe, Mayan, Aztec, Native Village of Barrow Inupiat Traditional Government, Nome Eskimo Community, etc.*

☐ Chinese
☐ Filipino
☐ Asian Indian
☐ Other Asian – *Print, for example, Pakistani, Cambodian, Hmong, etc.*
☐ Vietnamese
☐ Korean
☐ Japanese
☐ Native Hawaiian
☐ Samoan
☐ Chamorro
☐ Other Pacific Islander – *Print, for example, Tongan, Fijian, Marshallese, etc.*

☐ Some other race – *Print race or origin.*

**Kíni ìran Ẹni Kìíní?**

Sààmì sí ☒ àpótí kan tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ, KÍ O SÌ kọ àwọn lẹ́tà àwọn abínibí náà lọ́kọ̀ọ̀kan lái so wọ́n pọ̀.

- Aláwọ̀ Funfun — Kọ àwọn lẹ́tà náà lọ́kọ̀ọ̀kan lái so wọ́n pọ̀, fún àpẹẹrẹ, Ará Jámnì, Ará Áyálándì, Gẹ̀ẹ́sì, Ará Ítálì, Ará Lẹ́bánónì, Ará Íjíptì, abbl.
- Aláwọ̀ Dúdú tàbí Ará Afirika ní Amẹ́ríkà — Kọ àwọn lẹ́tà náà lọ́kọ̀ọ̀kan lái so wọ́n pọ̀, fún àpẹẹrẹ, Ará Afirika ní Amẹ́ríkà, Ará Jamáíkà, Ará Haiti, Ará Nàìjíríà, Ará Etiópíà, Ará Sòmálíà, abbl.
- Ará India ti Amẹ́ríkà tàbí Ọmọ-bíbí Alaska — Kọ àwọn lẹ́tà àwọn orúkọ (àwọn) ẹ̀yà tí a ti forúkọ wọn silẹ̀ tẹ́lẹ̀ náà, tàbí ti àwọn olórí (àwọn) ẹ̀yà náà lọ́kọ̀ọ̀kan lái so wọ́n pọ̀, fún àpẹẹrẹ, Navajo Nation, Blackfeet Tribe, Abínibí Maya, Ará Aztec, Native Village of Barrow Inupiat Traditional Government, Nome Eskimo Community, abbl.
- Ará Sháínà
- Ará Filipine
- India Ará Asia
- Ará Asia mìíràn — Kọ àwọn lẹ́tà náà lọ́kọ̀ọ̀kan lái so wọ́n pọ̀, fún àpẹẹrẹ, Ará Pákistánì, Ará Kàmbódíà, Ará Hmong, abbl.
- Ará Vietnam
- Ará Korea
- Ará Japan
- Ọmọ-bíbí Hawai
- Ará Samoa
- Ará Chamorro
- Àwọn Ará Erékùṣù Pàsífíìkì mìíràn — Kọ àwọn lẹ́tà náà lọ́kọ̀ọ̀kan lái so wọ́n pọ̀, fún àpẹẹrẹ, Abínibí Tonga, Ará Fiji, Ará Erékùṣù Marshall, abbl.
- Ìran mìíràn — Kọ àwọn lẹ́tà ìran tàbí abínibí náà lọ́kọ̀ọ̀kan lái so wọ́n pọ̀.

# Parí àwọn ìbèèrè náà fún ẹnìkọ̀ọ̀kan ti a fikún wọn

## A ó béèrè awọn ìbéèrè méjì tó wà ní ìsàlẹ̀ wọ̀nyí lọwọ ẹnìkọ̀ọ̀kan tí a bá fi kún wọn

*MÁṢE KỌ ÀWỌN ÌDÁHÙN RẸ SÓRÍ ÌTỌ́SỌ́NÀ YÌÍ*

**2. Does this person usually live or stay somewhere else?**
*Mark ☒ all that apply.*

- ☐ No
- ☐ Yes, for college
- ☐ Yes, for a military assignment
- ☐ Yes, for a job or business
- ☐ Yes, in a nursing home
- ☐ Yes, with a parent or other relative
- ☐ Yes, at a seasonal or second residence
- ☐ Yes, in a jail or prison
- ☐ Yes, for another reason

**Ǹjẹ́ ẹni yìí sábà máa ń gbé tàbí dúró sí ibòmíràn?**

Sààmì ☒ sí gbogbo èyí tó kàn.

- Rárá
- Bẹ́ẹ̀ni, fún ilé ẹ̀kọ́ kọ́lẹ́ẹ̀jì
- Bẹ́ẹ̀ni, fún iṣẹ́ ológun tí a pín fúnni
- Bẹ́ẹ̀ni, fún isẹ́ kan tàbí okòwò kan
- Bẹ́ẹ̀ni, ni ibùgbé ìtọ́jú aláàárẹ̀
- Bẹ́ẹ̀ni, pẹ̀lú òbí tàbí ìbátan mìíràn
- Bẹ́ẹ̀ni, ni àkókò kan lọ́dọọdún tàbí ilé kejì tí ènìyàn ńgbé
- Bẹ́ẹ̀ni, ninú ẹ̀wọ̀n tàbí ilé túbú
- Bẹ́ẹ̀ni, fún ìdí míràn

**3. How is this person related to Person 1?** *Mark ☒ ONE box.*

- ☐ Opposite-sex husband/wife/spouse
- ☐ Opposite-sex unmarried partner
- ☐ Same-sex husband/wife/spouse
- ☐ Same-sex unmarried partner
- ☐ Biological son or daughter
- ☐ Adopted son or daughter
- ☐ Stepson or stepdaughter
- ☐ Brother or sister
- ☐ Father or mother
- ☐ Grandchild
- ☐ Parent-in-law
- ☐ Son-in-law or daughter-in-law
- ☐ Other relative
- ☐ Roommate or housemate
- ☐ Foster child
- ☐ Other nonrelative

**Báwo ni ẹni yìí ṣe bá Ẹni Kìíní tan?**

Sààmì sí ☒ àpótí KANṢOṢO.

- Ọkọ/aya/ẹnikejì tí akọ-n-bábo rẹ̀ yàtọ̀
- Ẹnikejì tí akọ-n-bábo rẹ̀ yàtọ̀ láìsí ìgbéyàwó
- Ọkọ/aya/ẹnikejì tí akọ-n-bábo rẹ̀ jẹ́ bákan náà
- Ẹnikejì tí akọ-n-bábo rẹ̀ jẹ́ bákan náà láìsí ìgbéyàwó
- Ọmọ bíbí inú ara ẹni
- Ọmọ ọkùnrin tàbí obìnrin tí a gbà láti sọ di ti ara ẹni
- Ọmọ ọkọ tàbí aya ẹni l'ọ́kùnrin tàbí l'óbìnrin
- Ẹgbọ́n tàbí àbúrò l'ọ́kùnrin tàbí l'óbìnrin
- Bàbá tàbí ìyá
- Ọmọ-ọmọ
- Ìyá tàbí bàbá ọkọ tàbí aya
- Ọkọ tàbí aya ọmọ ẹni
- Ìbátan mìíràn
- Abánigbé-yàrá tàbì abánigbélé (roommate or housemate)
- Ọmọ tí a gbà tọ́ (foster child)
- Ẹlòmíràn tí kìí ṣe ìbátan

# Parí ojú ìwé kẹjọ tí o bá kà jù èniyàn mẹ́fà lọ

*MÁṢE KỌ ÀWỌN ÌDÁHÙN RẸ SÓRÍ ÌTỌ́SỌ́NÀ YÌÍ*




Jọ̀wọ́ fi ìwé ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò Gẹ̀ẹ́sì náà tí o ti kọ parí sínú àpò ìfiwéránṣẹ́ tí a ti sanwó fún náà tí o gbà, kí o sì fi ránṣẹ́.

## Ìkànìyàn **2020** náà rọrùn ju ti àtẹ̀yìnwá lọ.




### Ǹjẹ́ o mọ̀ pé o lè fèsì lórí ayélujára?

Bí o bá le parí Ìkànìyàn 2020 náà lórí ayélujára, lọ si URL tí a tẹ̀ sórí ìwé ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò náà.

### Àwọn Fídíò ìtọ́sọ́nà fún pípari Ìkànìyàn **2020** lórí ayélujára wà fún lílò ní

2020census.gov/languages

D-G (yor) Yoruba